LIBRARY

**OWE**

Eni a mba na'ja ni a ma nwo loju a ki i feti si ariwo ọja.


# Irohin Yoruba

No. 753 NOVEMBER 11 — NOVEMBER 17, 1959 Kobo Meji (2d.)


**LAKAYE ỌRỌ**

OKELE gbigbẹ, ti on ti alafia, o san ju ile ti o kun fun ẹran-pipa ti on ti ija lo.

IBAWI wọ inu ọlogbọn ju ọgọrun paṣan lọ ninu aṣiwere.

# OLOYE AWOLOWO DAGBERE FUN IGBIMO IJỌBA IWO-ORUN

IBADAN.

NI ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹta oṣu yi ti Ajọ Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun bẹrẹ ipade ni Oloye O'Olori Awolọwọ, Alagbere fun Ipinle Iwọ-na pe, on fi aye ... ni arin ajọ Igbimọ ... nitoripe on ntẹsiwaju lati wọ Igbimọ-Nla Aṣofin Apapọ Ijọba Naijiria. O ni aye Ajọ Igbimọ yi ni on sọ pe on fi silẹ ki iṣe Ipinlẹ Iwọ-Orun nitoripe Ipinlẹ Iwọ-Orun ni ile on.

Ninu ọrọ idagbere rẹ, o ni on dupẹ pe lati ọdun kẹjọ, lati ọjọ kẹdogun oṣu kini ọdun 1952 ti awọn ti di Alakoso Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun yi, on dupẹ lọwọ Olorun pe ọpọlọpọ iṣẹ idagbasoke ilu ni awọn ti ṣe ti ko le parẹ niwọn igbati aiye ba si wa. Ogo iṣẹ aṣeyọri na ni nwọn yio si ma a sọ itan rẹ pẹlu oruko awọn. Nitori awokọṣe ni awọn iṣe ti awọn ti ṣe na jẹ fun awọn Igbimo Ijọba Ipinle ilu Naijiria yoku.

O ni nigbati Ajọ Ipinlẹ Iwọ-Orun ti awọn nṣe Alakoso rẹ yi bẹrẹ ninu ọdun 1952, ọpọlọpọ awọn enia ni nwọn nfi oju ẹgan wo awọn wipe iṣekuṣe ni nwọn kan ma a lọ joko sibẹ ṣe, o ni: Ṣugbọn on dupẹ pe ibiti nwọn gbe fi oju si ona ko gba ibẹ. Gbogbo onilakaye aiye ni o nkan saara si awọn pe awọn ṣiṣẹ awọn ni aṣepe.

O ni lilọ ti on nlọ pẹkẹ kan ko le mi pẹlu Igbimo Ijoba Ipinlẹ Iwọ-Orun nitoripe awon Minista on ti o si wa nibẹ to ẹru na gbe ti ko fi ni yẹngen mo won lowọ ati awọn aṣoju Igbimo Ijoba na. O si ki awon Egbe Alatako Igbimọ Ijoba Ipinlẹ Iwọ-Orun fun ajumoṣepọ awọn nibiti awon gbe gbe e de yi.

Nigbati o pari ọrọ rẹ n' Ọgbẹni Dennis Osadebay

**Wo oju ... e kẹrindinlogun**



## Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun da iṣẹ Redio alaworan silẹ

IBADAN.

NI alẹ ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kọkanlelọgbọn oṣu ti o kọja yi ni Gbọngan Ijọba Ipinle Iwọ-Orun (Western Hall) ni Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ṣe eto a ti ma a lo redio alaworan ni Ipinlẹ Iwọ-Orun. Irufẹ eyi ti ko ti si ri ni gbogbo awọn ilu ilẹ Afrika. Oloye Awolọwọ ni awọn ohun diẹ ti o ṣẹlẹ ninu igbesi aiye on jẹki on ni idunnu pupọ lati wa a ṣe eto aṣeyẹ redio alaworan titun yi, o si ni o ni lati jẹ igberaga fun awọn ara Naijiria lati ri i pe IpinlẹIwọ-Orun Naijiria ni o ṣe iṣẹ ribiribi ti o joju to yi ti o si jẹ pe awọn ara ilu miran ni Naijiria nikan kọ ni nwọn njowu rẹ ti nwọn si fẹ ṣe irufẹ rẹ, ṣugbọn ọpọlọpọ awọn ilu kakiri Afrika ni nwọn tun fẹ lati ṣe bẹ ẹ pelu.

Oloye Awolọwọ ni Ijọba on da redio alaworan silẹ nitoripe o ni igbagbọ si i pe yio ṣe iranwọ lati mu ẹkọ lọ siwaju dada ati pe ẹkọ ni ... ilgmu idagbasoke wa ninu gbogbo nkan miran, o si

**Wo oju ewe kẹrindinlogun**

## Nwọn yẹ ọjọ ipade elere-bọlu Naijiria ati Egypt siwaju

AWỌN Elere Bolu Naijiria ati ti Egypt ti panupọ ye ojo ti nwọn fẹ pade gba bọlu ti nwọn ti fi si ọjọ Abamẹta ti ṣe ọjọ kejila oṣu ti mbọ yi si ọjọ keji ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu kanna.



Aworan yi ni ti awọn Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ti nwọn ba Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ya lẹhin ti o dagbere fun wọn tan, Oloye Awolọwọ na ni o wa ni ipo kẹtala lati ọwọ osi

# IROHIN KAKIRI ILẸ YORUBA

## Iwuye Iyalode Ẹgbẹ Afẹnifẹre dun pupọ

EBUTE IGBORO-ILARO.

AWỌN ara Ebute Igborọ fi Jarinatu A. Ọdẹyẹmi ọmọ Ilesha t'iṣe aya Ọgbẹni S. O. Bashorun jẹ oye Iyalode Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) lẹnulọlọyi, o si wa ṣe iwuye na ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹdogbọn oṣu ti o koja yi. Lati arọ titi di agogo mejila osan ọjọ na ni awọn ogunlọgọ enia ti pe sibẹ, gbogbo awọn ara ilu yi ni nwọn fẹrẹ pe si ibi aṣeyẹ na tan. Oloye na si fi iyan ati orişirisi awọn ohun mimu tẹ gbogbo awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na lọrun. Okọ Ol... paapa ṣe gud... nara. lọjọ na ... ju ohun ti ... tan sihin lọ.

... Diẹ ni a le daruko ninu awọn Ẹgbẹbirin Afẹnifẹre ti nwọn pe sibẹ ati awọn miran ti nwọn wa ba wọn ṣe aṣeyẹ ọjọ na ni awọn Iyaafin Jarinatu Abẹbi Ọdẹyẹmi; Biatisi Ọmọtọla, Olowookere; Ọmọkẹhinde; Abigeli Ojo, Şifawu Ọdẹyẹmi; Raliatu Ayinkẹ; M. A. Debẹodẹrọ (Baba-Ẹgbẹ); Amusa Balogun, Ambali Banijọ; N. Bello; E B Falana; Raimi Badaru ati B Oluọde.

Oye a mori o.

## Oku iya Ọlalekan dun

IGBAJỌ.

LAIPEYI ni Aderẹmi, iya Ọlalekan Bamigboye ku, awọn ọmọ rẹ mẹtẹta paapa Ọlalekan Bamigboye si fi jijẹ ati mimu tẹ awọn ogunlọgọ alabaşẹyẹ ọjọ na lọrun. Fun ẹyẹ isinku na, awọn ogunọdẹ onibọn yin iki ibọn pupọ nile. Orişirişi ilu bi gangan ati şẹkẹrẹ ati aro ni ọ pe si ibi aşeyẹ na, ọpọlọpọ awọn ... ajo ojo na ni ... ọjọ na laag... ọ le gongo ,irohin ko toafojuba ni.

Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn enia jankanjankan alabaşẹyẹ ọjọ na ni Oloye Ọbala, awọn Ọgbẹni J. S. Okẹ, A. T. Obadebọ, Faşeyitan, David Aiyepọla ati Layiwọla Adesiyan.

Ki Oluwa gbe oku na si afẹfẹ ire ki O si tun ẹhin rẹ şe.

## Asani şe ajọyọ ọdun baba rẹ

ILE-IFE.

OGBẸNI ASANI Bello Ajigbayin şe ajọyọ ọdun baba rẹ ni ọjọ Ẹti ti işe ọjọ keji oşu kẹwa ọdun yi, o si nawo nara. Awọn Ẹgbẹ Binukonu ti Ọgbẹni Bello Ajigbayin, ọkan ninu wọn şe gudugudu meje lọjọ na, nwọn nawo bi ẹlẹda. Ajọyọ ọjọ na pabambari, irohin ko to afojuba ni.

Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn alabaşẹyẹ ọjọ na ni awọn Ọgbẹni Isaac (Olori); Joseph Baruwa, Joshua Omiyẹra D. Gbọlade, J. F. Adodun; I. Adedire, J. Deyẹmi, S. Lodoko ati I. Ọlawọyin.

## Awọn Ẹgbẹ Afẹnifẹre bori ninu ibo Ijọba Ibilẹ Ijẹbu

IŞEGUN ti awọn ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) ni ninu ibo ti nwọn di ni ọjọ Abamẹta ti işe ọjọ kẹrinlelogun oşu ti o koja yi lati yan awọn aşoju sinu Igbimọ Ijọba Ibilẹ Ijẹbu ni Iha Ariwa fihan gbangba pe awọn ara ibẹ mọ riri işẹ Ẹgbẹ Afẹnifẹre nwọn si ni ifẹ gidi si ẹgbẹ na, o si tun iru aye ti ẹgbẹ na yio wa han nigbati nwọn ba dibo fun wọn lati wọle Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria.

Nigbati nwọn dibo na lati yan awọn aşoju mẹta sinu Igbimọ wọn na dipo awọn Kansilọ wọn mẹta ti nwọn fi aye na silẹ, gbogbo awọn ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre mẹtẹta ti nwọn yan sode ni nwọn yege ninu ibo na.

## Awọn ara abule Osu le baalẹ wọn kuro ni abule: ko fẹ ki nwọn sanwo ori

ILESHA.

LẸNULỌLỌYI ni awọn ara abule Osu le Oloye Jade Adekanye, Baalẹ na, ibuso kuro ni... o fi jinna si ilu ... Awọn ara abule na sọ pe afibi Baalẹ na ba kuro ni abule na fun awọn ni awọn nkan to le lọ dada nibẹ fun awọn.

Nigbati Ọba Aiaiyeluwa Adelupọ Ogunmokun, Fiwajoye Biladu Keta, Ọwa Ilesha ba awọn ijoye rẹ ati awọn aşoju abule na meji... ti nwọn wa si ọdọ di... ipade kan pọ ni ọjọ Ọjọbọ ti işe ogbọnjọ oşu ti o koja yi ni awọn aşoju na be Ọwa pe ki o kilọ fun Oloye Adekanye ki o maşe wa si itosi abule wọn fun anfani ara rẹ. Nwọn si fihan ninu iwe ẹbẹ ti nwọn mu fun Ọba na pe nitori ki iwa ti ko ni tẹ Ọba na ati awọn ijoye rẹ lọrun ma ba a şelẹ ni awọn ko şe jẹ lati ri Baalẹ awọn na ni abule awọn ati itosi ibẹ mọ.

Nwọn ni Baalẹ na ti nkọ awọn kan pe ki nwọn maşe san owo-ori, nitorina rogbodiyan nla ti şẹlẹ ni abule na. Nwọn pe Baalẹ na t'o ti wa si Ilesha pe ki o da si ipade na şugbọn ko yọju sibẹ rara. Ọba na si fi awọn ara abule l'ọkan balẹ pe on yio şe ofintoto nipa ọran na, on yio si jẹki awọn ara abule na mọ ipinnu on lori rẹ.




## AKIYESI PATAKI

EYI ni lati fi kede fun gbogbo ẹnyin onkawe wa wipe ti ẹ ba nkọwe si wa ki ẹ ma a kọ o yanju nitoripe ọpọlọpọ ni iwe ti a nri gba ti o jẹ pe pẹlu inira ni a o fi ri idaji ka ninu rẹ, nipa bayi a ko le tẹ iru iwe bẹ ẹ jade fun kika.

Fun awọn ti o nbinu pe iwe wọn ko jade tabi ko tete jade a fẹ k. ẹ mọ pe iwe ti a nri gba larin ọsẹ kọọkan to ọọdun (300), iwọn iba ti a ba si ri aye fun ni a o tẹ jade, oribande ni, ki işe ọran yan. Ẹniti o ba si fẹ ki ti on jade ni ọranyan ki o şe e ni ipolowo-ọja, eyini ni pe ki o fi owo ti o to tẹ ẹ jade şowọ....Pọnun kan ni aye inşi kan (£1 per single column inch), bi o ba si ti pọ to ni owo rẹ yio fi pọ to

Bi ẹnikẹni ba si fẹ şe aşoju wa, tabi ti o ba şẹşẹ fẹ ma a gba iwe tabi ti ko ba ri iwe rẹ gba laseko, ki o ma a kọwesi:—Circulation Manager, Amalgamated Press Ltd., P O. Box 163 Lagos Nigeria, yio si gbọ esi. Bi ẹ ba fẹ sọro nipa ohun ti o jẹmọ irohin nikan ni ki ẹ ma a kọwe si Olotu ati pe ni ọjọ 'Ru (Wednesday) ni iwe na tun njade nisisiyi ki işe ọjọ Aje mọ. Ajumọşe wa ko ni bajẹ o.

OLOTU.

# Ọlọrunnisọla ko ọmọ jade

JOS

[illegible]

## Adajọ sọ ẹniti o ti aya arakunrin rẹ mọle sẹwọn oṣu kan

BADAGRY

[illegible]

## Ẹ dibo F'Ọpẹ

# Awolọwọ larin awọn ara Ipinlẹ Iwọ-Orun



Eyi ni aworan ipade ti Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ba awọn ara ilu Ubiaja ṣe. O n na ni o duru ti o njuwọ larin awọn ọgọnlọgọ enia ti o npe ayẹni rẹ



Aworan yi ni ti igbati awọn obirin ara ilu GBOKODA nfi ọkọ-ajẹ ṣe ẹyẹ fun Oloye Awolọwọ, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun nigbati o ṣe ipolowo idibo kakiri Ipinlẹ Ila-Orun

## Adajọ sọ apẹlẹwọn kan si ẹwọn ọdun meji

IFE

[illegible]





Ẹnyin paapa le tubọ rẹwa si i ti ẹ ba nlo ọṣẹ Lux


### AKIYESI

Enikẹni ti o ba mọ itan awọn Ọba ile Yoruba, iba ṣe eyiti o ti kuni tabi eyiti o si wa laye, ki o kọọ sọwọ, tabi bi awọn ti ṣe tẹ ilu kọọkan ati eyikeyi ninu itan iṣẹdale Yoruba. A o si tẹẹ jade fun anfani gbogbo enia. Ẹ ku iṣẹ o.

OLOTU


## ẸRỌ PHILIPS
## *TITUN* TI O NPARO REKODU
### pẹlu ọpọlọpọ anfani—mọkanlelogun ni wọn!

21



PHILIPS WEST AFRICA LTD., LAGOS

# AṢA IṢẸDALẸ YORUBA

Ni igba lailai k'awọn Oyinbo to o de ilẹ wa, ti o si si ọlaju iwe-kika tabi kikọ rara, awọn Yoruba ni ami kan ti nwọn ma a nlo ṣọwọ sira wọn ni idalẹ bi iwe-kikọ (letter) tio si jẹ wipe, bi nwọn ba ti ri ami yi, ọrọ wọn ti ye'ra wọn, oruko awọn ami na ni a npe ni "AROKO".

Diẹ ninu awọn ami na niwọnyi:—

1. Orin ti a nrun (pako)
2. Iyẹ adiẹ tabi ti ẹiyẹle
3. Awọ oju ilu
4. Owo ẹyọ
5. Irepe aṣọ funfun
6. Irepe aṣọ dudu
7. Ajaku akisa aṣọ
8. Eedu oju aaro
9. Ata-jijẹ
10. Ewe tabi horo inu ọsan agbalumọ
11. Ẹfun
12. Osun
13. Mariwo Ọpẹ
14. Iya Aje (Olu-Aje tabi owo ẹyọ nla)
15. Ọpa Ilẹkẹ
16. Ẹdan Ogboni
17. Ekanna ẹsẹ adiẹ
18. Ọpẹle Ifa.

Bi nwọn ti ṣe nlo awọn ami na ati itumọ wọn niwọnyi:—

Pako:—Bi a ba fi Pako ranṣẹ si enia, itumọ eyi ni wipe ẹniti o fi pako na ranṣẹ fi iwe han pe on fẹran rẹ gidigidi.

Iyẹ-ẹiyẹ: Bi ẹnikan ba fi iyẹ-ẹiyẹ ranṣẹ si ẹnikẹji rẹ nigbati ija wa larin wọn ti ija na ko si ti i pari itumọ eyi ni pe ija na ti tan ninu ẹniti o fi ami na ranṣẹ patapata nitoripe "iyẹ-ẹiyẹ ki i wọ ẹiyẹ lọrun".

Awọ-oju-ilu: Bi nwọn ba fi awọ-oju-ilu ranṣẹ si ẹniti o wa ni idalẹ, eyi jẹ ami pe ki o tete wale kiakia, nwọn nfẹ ri oju rẹ nile o.

Owo-ẹyọ: Itumọ fun owo-ẹyọ wa lorişirişi. Bi a ba da oju eji owo-ẹyọ kọ ara wọn, ti a fi owu dudu ati funfun we e papọ, ti a si fi ranṣẹ si ẹniti o wa ni idalẹ; itumọ rẹ ni pe ki oluwarẹ tete wale ki a fi oju kan ara wa o.

Bi a ba da ẹhin eji owo-ẹyọ kọ ara wọn, ti a si we e ni owu dudu ati funfun, ti a si fi ranṣẹ si enia, itumọ eyi ni pe ọrẹ kọ si larin awọn mejeji mọ, atunṣe ko si si fun ọrọ na mọ.

Bi a ba fi owu we ẹta owo-ẹyọ, ti a si fi ranṣẹ si enia, itumọ rẹ ni pe, a ta oluwarẹ danu patapata.

Bi a ba fi owu we ẹfa owo-ẹyọ, ti o si fi ranṣẹ si ẹniti o wa lokere, itumọ eyi ni pe, ki ẹni okere na tete wale kiakia.

Bi a ba fi owu di ẹwa owo-ẹyọ, iyẹ-adiẹ ati eekanna ẹsẹ adiẹ papọ, ti a si fi ranṣẹ si ẹniti o wa ni ilu okere, itumọ rẹ ni pe, ... adiẹ ba tanle ... o ba kan ohun ... o nwa, nṣe ni i pada wale, ki oluwarẹ tete wa le o.

Bi a ba fi owu di ẹjọ owo-ẹyọ papọ ti a si fi ranṣẹ si enia ni idalẹ, itumọ rẹ ni pe, a dupẹ ore ti oluwarẹ ti ṣe fun ni ti o jọ ni loju.

Irepe aṣọ-funfun: Bi a ba fi irepe aṣọ funfun ranṣẹ si enia lokere, o jẹ ami rere fun ẹniti a ba fi ranṣẹ si, yalaa lori ọrọ ẹjọ tabi ti ede-aiyede larin ọrẹ, ẹbi tabi ni ile ana ẹni paapa.

Irepe aṣọ dudu ati Edu: Bi nwọn ba fi adilu irepe aṣọ dudu ati edu ranṣẹ si enia ni ilu okere, eyi jẹ irohin buruku lati ile wa fun oluwarẹ.

Irepe aṣọ akisa Bi nwọn ba fi irepe aṣọ akisa ranṣẹ si enia, eyi jẹ ami pe nwọn korira ẹniti nwọn fi ranṣẹ si na, nwọn si kọ o silẹ patapata, nitoripe, akisa ki i ribi gbe ninu ile, ẹnikẹni ni o ma a nyẹra fun un.

Ata-jijẹ: Bi nwọn di'ata-ṣọwọ si enia, eyi jẹ ami pe, ẹniti o di ata na ṣọwọ wa ninu ibanujẹ tabi ipọnju

Ewe ọsan tabi horo ọsan agbalumọ: Bi nwọn ba di ewe ọsan tabi ṣẹsan agbalumọ ṣọwọ si enia lokere, eyi jẹ ami wipe, ẹniti o fi ami na ṣọwọ wa ninu ayọ, alafia ati idunnu pupọ, nitoripe, sisan ni o nsan ọsan ti inu rẹ si ma a dun.

Ọpa ilẹke: Bi Ọba ba fi ọpa ilẹkẹ ṣọwọ si enia, eyi jẹ ami ijaiya pupọ, nitoripe pipe ni Ọba nfi Ọpa Ilẹkẹ pe enia pe ki o wa ni kiakia.

Edan Oṣugbo: Bi ẹdan Egbẹ Oṣugbo ba ... enia, eyi jẹ ami ... o si yatọ diẹ si ti Ọpa Ilẹkẹ bi ọfọ nla ba ṣẹ ọkan ninu awọn Ẹgbẹ Oṣugbo ni nwọn ngbe ẹdan Oṣugbo ranṣẹ si oluwarẹ lati fi tufọ fun un. Bi ọkan ninu Ẹgbẹ Oṣugbo ba si nja ajaigbila, bi nwọn ba gbe ẹdan Oṣugbo ranṣẹ si oluwarẹ, ija na gbọdọ tan ninu oluwarẹ lẹsẹkẹsẹ.

Ọpẹlẹ Ifa Babalawo: Gẹgẹbi Ẹdan Oṣugbo ti jẹ fun awọn Ẹgbẹ Oṣugbo ni Ọpẹlẹ Ifa Babalawo jẹ fun awọn Ẹgbẹ Babalawo pelu.

Adipọ Aroko: Bi nwọn ba fi adilu Ẹfun, osun, mariwo ọpẹ, horo ọsan agbalumọ tabi ṣẹsan ranṣẹ si enia lokere, eyi jẹ ami oluwarẹ pe lati ile wa fẹ ... enia rẹ ati gbogbo ... ni alafia ara, inu-ile, ... ati ayọ ailopin, eyi si tun fi fẹ ti o yẹ kooro ti o si daju han lati ọdọ ẹniti o fi ranṣẹ. Awọn Babanla wa a si ma a fi eyi ṣe adehun larin ilu meji ni aiye igbaani pe ki o ma fi le si ibinu, ogun tabi ijamba larin awọn enia wọn.

## Lati ọwọ D. O. Ẹgẹ, Ita Ẹgẹ, Ibadan

# Isinku Ajibade dun

KISHI.

Ni ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kẹsan oṣu ti o kọja yi ni Ọgbẹni Ajibade Akande ... marun silẹ, ku, o si fi ... wọn lo si pe si ibi ... isinku na. Awọn ọmọloku na ni awọn Oyinlade Ajibade, Taffa Ajibade, Adetayọ Ajibade, Adedokun Ajibade, Adeniran Ajibade ati Sinbi Ajibade.

Gbogbo awọn ọmọlẹbi oku ati awọn ọrẹ awọn ọmọ'loku ni o pe ṣọṣọ ti nwọn si nawo-nara fun odidi ọjọ mẹta ti nwọn fi njo kiri. Ẹhin oku na a dara o.



Aworan yi ni ti ikomọ ọmọbirin ti Dọkita P. O. Rosanwo ati aya rẹ ṣe ni ọjọ
keji oṣu yi ninu ile wọn ni Yaba. Orukọ ọmọ titun na ni Olurẹmi Abisọye Adeọla.
Awọn ti o wa ninu aworan na lati apa osi Ọgbẹni Afọlabi Aina, Henry Rosanwo
ti o nṣiṣẹ ni ile-iṣẹ Ports Authority l'Apapa, Dọkita Rosanwo, Iyaafin Rosanwo ti o
gbe ọmọ lọwọ, J. O. Rosanwo ti ile-iṣẹ Amalgamated Press Ltd. l'Eko ati ẹgbọn-
aburo na, Gabriel Bọladele Rosanwo pẹlu awọn ijọ won lati Yaba Baptist Church.




# IROHIN LATI ILU OYINBO

## Olori ilu Amerika ngni ilera dada

WASHINGTON.

NI ojo Abameta ti ise ojo kokanlelogbon osu ti o koja yi ni Olola Eisenhower, Olori ilu Amerika jade ni Ile-iwosan "Walter Reed Hospital" lehinti o ti lo wakati merinlelogun nibe fun ayewo ti i ma a lo se lodoodun.

Onisegun-agba Leonard D. Heaton ti o se ise fun Olori ilu Amerika na ni: o ni ilera daradara ju ti atehinwa lo. Nse ni on 'paapa beresi rerin pelu igbadun nigbati o njade bo lati Ile-iwosan na.

Sugbon Iwe-irohin ti o jade lati Ile Ijoba Amerika ni pe Olori ilu na ngni ilera -kun-ilera ni a fi ti al'r arun ona-ofun (trecheo brochities) ti o ti mba a ja.

## Iya Obabirin Geesi ti ngbadun

LONDONU.

NI ojo Abameta ti ise ojo kokanlelogbon osu ti koja yi ni awon Onisegun ti ntoju Ololajulo Ayaba na Elizabeth ti ise Iya Obabirin Geesi wa se ayewo re ni Afin re "Clarence House" nwon si so pe o ngbadun daradara, nwon ni ireti pe yio beresi se gbogbo ohun ti o ba ni lati se laipe yi.

## *Awon akeko Naijiria ni ilu Oyinbo ni ki Ijoba pa aye gbakeji Gomina-agba re*

LONDONU.

AWON Egbe Akeko Naijiria ti o wa ni ilu Geesi ati ti Ireland panupo kesi Apapo Ijoba Naijiria pe ti Olola Ralph Grey ti o wa ni ipo Gbakeji Gomina Agba nisisiyi ' a lo ki nwon pa aye ipo na re patapata.

Ninu iwe ikede kan ti o jade ni ojo Isegun ti ise ojo keta osu yi lori iwadi Igbimo Solaru nipa fi fi omo Naijiria si aye giga (Nigerianisation) awon Egbe Akeko ni: Ijoba Naijiria ti fi aye gba Gbakeji Gomina-Agba ju, iru eyiti Ijoba kankan ko je gba.



Aworan yi ni ti awon "Omidan Rhodesia ati Nyasaland", Omidan Vivian Lentin, eni odun metadinlogun "Omidan Ghana", Omidan Star Annan, eni ogun odun ati Omidan Hong Kong Michele, Mok, eni odun metadinlogun, awon meteta je arewa obirin ti o wa ni Savoy Hotel ni Londonu. Laipe ni olukuluku won ba oko-ofurufu fo wa si Londonu lati ilu re. Awon obirin meteta na wa ninu awon ogoji arewa obirin tabi jubeelo ti yio jo ijo ije ni ojo kewa osu yi ni "Lyceum Ballroom" fun yiyan "Miss World 1959". Ni Savoy ni awon obirin meteta ti o wa ninu aworan yi, lati owo osi si owo otun, ngbe.

* * *

## Ijebu Parapo dapomo gbe ..fenfere se ipade

IJEBU-ODE.

LENULOLOYI ni awon Egbe Ijebu Parapo dapomo Egbe Afenifere (Action Group) se ipade pataki kan ni ile Alhaji B. R. Alatishe, Baba-egbe won ni deede agogo merin irole nwon si se akanse adura fun Egbe Afenifere ati Oloye Obafemi Awolowo, Olori Egbe na ati Alakoso Ijoba Ipinle Iwo-Orun.

Nwon ni pelu Ogo Oluwa Egbe Afenifere ni yio bori ninu idibo gbogbogboo ti nwon yio di awon asoju wo Igbimo Apapo Ijoba Naijiria laipe ojo yi, bi nwon si ti nse adura ni nwon nyonmo Awolowo ti nwon si nkorin "Awo! Awo!! Awo!!! niso ni Fediral, ile baba omo k i iba omo leru," orin yi si gbojikan yika ibi ipade na.

Nwon ni Egbe Afenifere nikan ni egbe oselu ti o ti sise ribiribi fun ilosiwaju Naijiria, nwon si menu kan ile-iwe ofe ti egbe na ti dasile ati opolopo ise rere miran pelu ti nwon ti se, nwon s se ipinnu ki nwon to mu ipade na wa si opin lati parapo dibo fun Egbe Afenifere.

Die ti aye wa fun lati daruko ninu awon Oloye ati omo egbe na ni awon Ogbeni Yesufu Gbadamosi (Gbakeji Baba Egbe); M. K. Awokoya (Akowe Egbe); L. Awofusi (Gbakeji akowe Egbe ati Alamojuto Ilosiwaju Egbe); Ezikiel Opa-Aje (Akapo); Tijani Bakare; Ganiyu Olufowobi; J. Fowowa; S S Adebona; T Dongo; Agunbiade; A. A Adebanjo ati Buari Kadiri





PHILIPS

West African RECORDS

Wholesale Distributors:

Badejo Stores, 5 Olorogun St., Lagos
Dayo Development Co., 161 Victoria St., Lagos
Joss Ola Fajumolu & Bros., 21 Balogun St. West Lagos
Nwosu Bros. Stores, 24 Asa Rd., Aba
Ebele Egbunam Stores, 38 Church Road, Kano
Olasinboh Business Enterprise, P.O. Box 53, Kano.
Ezenweako Trading Stores 48 Aggrey Road, Port Harcourt.

PHILIPS (W.A.) LTD. P.M.B. 2023 Lagos




Aworan ti o wa ni oke yi ni ti oko awon ajagun l'oju omi ti ijoba Apapo Naijiria. ti oruko re si nje H M N S Nigeria, on si ni oko ologun kinni fun Ijoba Apapo Naijiria ti yio ko gunle si ilu yi. Oko yi gun! si Ebute Ehingbeti l'Eko ni ijarun ti ise ojo Abameta. Ogunlogo awon ena ni nwon si lo wo inu re.

# IROHIN LATI OKE-OKUN ATI OKE-ỌYA



Aworan oke yi ni igbati Ọgbẹni Harry K. Manigian, ọkan ninu awọn akede iṣesi ọran Ilu Amẹrika larin awọn ara ita, mba awọn olukọni ilu Kaduna ati agbegbe rẹ sọrọ lori nkan pataki ti apapọ Ijọba Orilẹ-ede jẹ. Ninu ọrọ rẹ Ọgbẹni Manigian fi ẹnu kan ibi ti iṣẹ awọn apapọ Ijọba Apapọ Orilẹ-ede ṣe kan Ipinlẹ Iwọ-Orun Afrika. Ni ile Ifiwe-pamọ ti Amẹrika ni Kaduna ni Ọgbẹni Manigiae ti ba awọn olukọni na sọrọ yi nigbati nwọn nse iranti ọjọ Apapọ Ijọba Orilẹ-ede.

## Ẹgbẹ Afẹnifẹre ṣe ipade

MANGOASE-GHANA.

NI ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹtadinlọgbọn oṣu ti o kọja yi ni awọn ọmọ oloku, ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre, ẹka Oke-Okun ṣe ipade, Ọgbẹni Bello Akọgun ni o ṣe alaga, Imam-Agba si ni o fi adura si ipade na, Ọgbẹni Jinadu Lambẹ si gbe e lẹsẹ. Nwọn ... Ijọba Ẹgbẹ Afẹnifẹre nwọ... so ọpọlọpọ ọro iwuri nipa ... Oṣelu na, nwọn si ṣe aṣaro ... awọn yio ti ṣe ma a ni ilọsiwaju nigbagbogbo ki nwọn to mu ipade na wa si opin.

Diẹ ti aye wa fun lati daruko ninu awọn ti o wa si ibi ipade na ni awọn Ọgbẹni S. A. Aiboye, Aṣoju Iwe "Irohin Yoruba" ni Akwatia, Jimo Ajani, Jimo Ijakodọla, Garuba Elẹṣin, S. A. Onibudo ati Abudu Raimi Japo.

Ẹ ma a ka Iwe
IROHIN YORUBA
nigbagbogbo fun
irohin aladun

## Ina nla jo ni Kaduna

KADUNA.

NI ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kejidilọgbọn oṣu ti o kọja yi ni ina nla kan ṣẹlẹ ni abule Abakpa, ile mẹta ni o jona patapata nibẹ ki nwọn to le pa ina na, awọn ọlọpa si sọ pe awọn fura si i pe ẹnikan ni o ti ina bọ awọn ile na.

Nigbati o si tun di alẹ ọjọ Eti ti iṣe ọgbọnjọ oṣu kanna ni ina nla keji tun ṣẹlẹ ni ọja Kaduna nla. O le ni ogoji iso-ọja ti o jona patapata nibẹ. Awọn ẹru ti o si ṣofo to onigba pọnun (£200), o to wakati mẹta gbako ti awọn Panapana fi ba ina na jijakadi ki nwọn to le pa a, omi ti nwọn lo si pipa rẹ to ẹgbẹrin (800) galọnu.

Awọn ọlọpa si wa lẹnu iwadi ohun ti o fa ina na ṣugbọn nwọn sọ pe awọn lero pe aikobikita-to ni o fa ina ti o ṣẹlẹ lọja na Sarkin Hausa (Olori-ọlọja) si ṣe ikilọ fun gbogbo awọn onisọ-ọja ni ọjọ na pe, panuikọle ni ki nwọn fi tun iso wọn ti o jona kọ ki ijamba ina ma ba a le tun ṣẹlẹ mọ.



Aworan yi ni ti awọn ọmọ-iya meji Mbuk Ndem ọmọ ọdun marun ati Arit Ndem, ọmọ ọdun meje ti nwọn gba kalẹ lọwọ ewu ijamba ina na.

**Ẹ ma a polowo ọja nyin sinu iwe "Irohin Yoruba"**

Iwọ yio ri i pe ẹwu rẹ
L'OMỌ JU **OMO**
Lofi fọ o



Wo iyatọ larin awọn ẹwu mejeji yi—bẹ ẹ nwọn ṣẹṣẹ fọ awọn mejeji tan ni! Eyi ti nwọn fọ ninu Omo ni o mọ ti o si tan—O mọ gara to bẹ ẹ gẹ.
Gbogbo awọn ẹwu nyin olorişirişi awọ ati funfun ni yio si mọ dada ti yio si ma a tan ti o ba fọ wọn ninu Omo.

**OMO** ni o nfọ aṣọ mọ julọ ni gbogbo agbaiye!



